# IWAASU LORI OKE, APA KEJI

## Matteu 6:1-34

## ẸKỌ 20 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ tò iṣura jọ fun ara nyin li ọrun" (Matteu 6:20).**

Oluwa korira agabagebe. Nigbakuugba ni Jesu maa n ṣe alabapade awọn akọwe ati awọn Farisi, inu Rẹ̀ si kun fun irunu ododo lati ri iwa buburu ọkàn wọn nigba ti wọn n gbiyanju lati fara han gẹgẹ bi onitara ọmọlẹhin Ọlọrun. Oun kò lọra lati sọ fun wọn pe wọn jẹ "ibojì funfun, ti o dara li ode, ṣugbọn ninu nwọn kún fun egungun okú, ati fun ẹgbin gbogbo" (Matteu 23:27).

### Adura Agabagebe

Awọn Farisi fẹran ki awọn eniyan maa ri wọn nibi ti wọn n gbadura. Wọn a maa duro ninu sinagọgu ni Ọjọ-isinmi, wọn a si maa gbadura gigun si Ọlọrun, wọn tilẹ maa n gbadura paapaa ni igun igboro ilu, ki eniyan pupọ ba le maa wò wọn. Jesu wi pe Isaiah ti sọ asọtẹlẹ daradara nipa wọn nigba ti o wi pe, "Awọn enia yi nfi ẹnu wọn sunmọ mi, nwọn si nfi ète wọn bọla fun mi; ṣugbọn ọkàn wọn jìna si mi" (Matteu 15:8). Jesu sọ fun awọn ti wọn n fi eti si ti Rẹ̀ pe ki wọn ma ṣe dabi awọn keferi ti wọn rò pe a o gbọ ti wọn nipa ọ̀rọ pupọ.

O mọ̀ pe awọn ọmọ-ẹyin Budha ni kẹkẹ́ adura, nigba miiran agbá nla ti a kọ adura si lara. Nigbakuugba ti kẹkẹ́ naa ba yi po, wọn gba a si pe wọn ti gbadura niyẹn. Awọn ara China paapaa maa n fi awọn adura wọn sori awọn kẹkẹ́ omi, ki wọn ma ba ṣe aapọn lati ṣẹṣẹ maa yi i kiri. Yoo rọrun lati gba adura pupọ lọna bayii, ṣugbọn Jesu ki i gbọ́ iru adura bẹẹ. Awọn "keferi" miiran gba pe mimi ori wọn lọna bakan jẹ adura gbigbà, wọn a si maa joko fun akoko pipẹ pẹlu ori wọn ti o n mi siwá sẹyin. Ni orilẹ-ède wa paapaa, awọn eniyan wà ti wọn rò pe wọn le ri idariji fun ẹ̀ṣẹ nipa kika adura kan, boya ni igba mẹẹdọgbọn tabi aadọta igbà, gẹgẹ bi ẹyẹ ayekootọ. Gbogbo iru adura bẹẹ jẹ ti agabagebe.

### Awọn Aṣẹ Jesu nipa Adura

Jesu sọ fun awọn eniyan Rẹ̀ lati wọ inu iyẹwu wọn lọ nigba ti wọn ba n fẹ ba Ọlọrun sọrọ, ki ohunkohun ma ba di adura wọn lọwọ. A le gbadura bẹẹ ninu ipade pẹlu. A le gbagbe ohun gbogbo ti o yi wa ká, ki a si gbadura bi ẹni pe a nikan wà ninu iyẹwu wa. Njẹ o ti i ri awọn ọmọde ti wọn gbadura kikankikan fun iṣẹju diẹ, lẹyin naa ki wọn yọju laaarin iho ọmọ-ika ọwọ wọn lati wò boya ẹni kan n ṣọ́ wọn? Wọn n gbadura ki eniyan le ri wọn, ki i ṣe pe wọn n bá Ọlọrun sọrọ rara. Ọlọrun ki i fi eti si iru adura bẹẹ.

Nigba ti a ba n ba Ọlọrun sọrọ, a gbọdọ ranti pe a wà niwaju Ọlọrun Mimọ́, Ẹni ti O da Ọrun on aye, a si gbọdọ ṣọra ki a ri i pe a wá si iwaju Rẹ̀ pẹlu ọ̀wọ̀. O ranti igba ti Isaiah wà ninu Tẹmpili ti serafu kigbe pe: "Mimọ́, mimọ́, mimọ́, li OLUWA awọn ọmọ-ogun, gbogbo aiye kún fun ogo rẹ̀." "Awọn òpo ilẹ̀kun si mì nipa ohùn ẹniti o ké, ile na si kún fun ẽfin" (Isaiah 6:3, 4). Ẹni ti o ni ọlá, ti O tobi ti O si lagbara ni Ọlọrun wa! Bawo ni a gbọdọ ti ṣọra to lati wá siwaju Rẹ̀ pẹlu isin tootọ ati iyin!

Ṣugbọn Jesu kò fẹ ki a maa foya nitori Oun. Nigba ti O kọ́ awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lati gbadura, O bẹrẹ pe, "Baba wa ti mbẹ li ọrun." Awọn ọmọ ti awọn obi wọn ba fẹran ki i foya wọn. Ọlọrun si n fẹ ki a wá sọdọ Rẹ̀ gẹgẹ bi a o ti beere nnkan lọwọ baba wa. O wi pe obi kò jẹ́ fun ọmọ rẹ̀ ni ejo nigba ti o ba beere ẹja, tabi okuta nigba ti o beere akara. Ọlọrun tobi ju bẹẹ lọ, O si fẹran wa lọpọlọpọ ju bi awọn obi wa ti fẹran wa, ati pe dajudaju Oun yoo dahun awọn adura wa.

### Gbigbadura Nigba Gbogbo

O ti di ara fun Onigbagbọ́ lati gbadura gẹgẹ bi o ti di ara fun eniyan lati mí – ati pe o jẹ́ dandan. Bi a ba dakẹ́ adura gbigbà, a o kú nipa ti ẹmi. Iwọ le wi pe, "Bi Ọlọrun ba mọ ohun ti mo ṣe alai ni, ki ni ṣe ti n o gbadura?" Nitori Jesu sọ fun ọ pe "Ẹ mã gbadura li aisimi" (1 Tẹssalonika 5:17). Adura maa n wà ninu ọkàn Onigbagbọ́ ni gbogbo igba, ati ni akoko aini yoo jade lọgán. Njẹ o ha ti ni ọgbẹ́ ninu ika-ọwọ́ rẹ ti o fun ọ ni irora kikankikan, lẹsẹkẹsẹ lọgan adura a jade lati inu ọkàn rẹ pe, "Ọlọrun, ràn mi lọwọ!" Adura naa wà nibẹ, ti o mura lati tọ Ọlọrun lọ.

Ọmọ Ọlọrun ni Jesu i ṣe, ṣugbọn O gbadura ni igba pupọ. Nigba miiran Oun a maa nikan lọ si ori oke, A si maa gbadura ni gbogbo oru. Ni oru ọjọ naa, ni Gẹtsemane, O gbadura kikankikan ti o fi jẹ́ pe "Õgùn rẹ̀ si dabi iro ẹ̀jẹ nla." O gbadura fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀; O gbadura paapaa fun Peteru ti aarẹ ti mú; O si sọkun lori awọn eniyan Jerusalẹmu ti wọ́n jẹ ọta Rẹ̀.

Ki i ṣe pe eniyan jẹ alailera tabi "ojo" bi o ba ṣẹ́ omije nigba ti o ba n gbadura. Jeremiah, ọ̀kan ninu awọn wolii nla Ọlọrun, ni a n pè ni "wolii ẹlẹkun," nitori o n sọkun o si n gbadura lori ẹ̀ṣẹ awọn eniyan. Dafidi wi pe,

"Ẹniti nfi ẹkun rìn lọ, ti o si gbé irugbin lọwọ, lõtọ, yio fi ayọ̀ pada wá, yio si rù iti rẹ̀" (Orin Dafidi 126:6). Paulu wi pe oun ti sin Oluwa pẹlu "irẹlẹ ọkàn gbogbo, ati omije pipọ" (Iṣe Awọn Apọsteli 20:19). Ọdọmọkunrin kan ṣe aisan pupọ o si sọ fun iya rẹ lati gbadura fun oun; o n fẹ iranwọ gan an. O wi pe, "Kigbe soke, ki o si gbadura!" Nigba ti a bá "kigbe" gan an niwaju Oluwa, ti a si mu ifẹ ti ara wa kuro, Oun yoo gbọ yoo si dahun.

"Ifẹ tirẹ ni ki a ṣe, bi ti ọrun, bẽni li aiye." Awọn ọrọ wọnyii wà ninu adura ti Jesu n kọ́ awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lati gbà. Nigba ti O wà ninu ọgba nì, ti O ngbadura pẹlu irora nla, O wi pe, "Jẹ ki ago yi ki o kọja kuro lori mi." O lè ro pe o daju pe Ọlọrun yoo dahun iru adura ti O fi itara bẹẹ gbà. Ṣugbọn Jesu yara fi kun un pe, "Ifẹ ti emi kọ́, bikoṣe tirẹ ni ki a ṣe." Ki i ṣe ifẹ Ọlọrun lati jẹ ki O bọ lọwọ kikan mọ agbelebu, nitori naa boya o rò pe awọn adura Jesu kò ṣe rere kan rárá. Ṣugbọn wọn ṣe. Jesu ṣẹgun ifẹ ti ẹran-ara ti O gbé wọ̀. O fi gbogbo ifẹ, gbogbo ero, gbogbo eemi igbesi-aye Rẹ̀ rubọ lati ṣe ifẹ Ọlọrun. Eyi ni nnkan ti Ọlọrun n reti lati ọdọ awọn ọmọ Rẹ̀. Ki i ṣe pe awọn yoo jẹ iru iya nla ti irora ati ibanujẹ ti Jesu jẹ, ṣugbọn o dabi ohun nla lati fi ifẹ inu eniyan fun Olugbala. Nitori naa nigba ti a ba wa fi ẹbẹ wa hàn fun Ọlọrun, a gbọdọ fi kun un pe, "Bi o ba jẹ ifẹ Rẹ̀." O daju pe, bi a ba fẹran Ọlọrun ju ohunkohun miiran lọ ninu aye, kò ni ṣoro lati wi pe, "Gẹgẹ bi Iwọ ti fẹ ẹ."

**"Lati Ọdọ Ẹni ti Gbogbo Ibukun ti n Ṣàn"**

"Fun wa li onjẹ õjọ wa loni." Njẹ o tilẹ duro lati ronu pe Baba wa Oninuure ti n bẹ ni Ọrun ni O fun ọ ni gbogbo ounjẹ ti o n jẹ ati aṣọ ti o n wọ̀? Njẹ o ni ọkàn imoore fun aanu Rẹ̀ si ọ? Ni orilẹ-ede yii, Ọlọrun ti fun wa ni ohun gbogbo lọpọlọpọ, ṣugbọn nigbakuugba ni a n ka itan awọn ajihinrere ti Ọlọrun rán si orilẹ-ède ti o ṣe alai ni, nibi ti kò rọrun lati ri ounjẹ ti o to jẹ. Wọn gbadura si Ọlọrun, wọn si mọ̀ pe nitori Ọlọrun ni o rán wọn lọ sibẹ̀, Oun yoo pese fun wọn. Ọlọrun n ṣe iṣẹ iyanu pupọ ni pipese fun aini wa.

Njẹ o ti i ṣe akiyesi awọn ẹyẹ ri, ki o si maa yà ọ lẹnu bi wọn ti ṣe le ri ounjẹ ti o to jẹ, paapaa ni igba otutu? Jesu wi pe, "Ẹ sá wò ẹiyẹ oju ọrun; nwọn ki ifunrugbin, bẽni nwọn ki ikore, nwọn ki isi ikójọ sinu abà, ṣugbọn Baba nyin ti mbẹ li ọrun mbọ́ wọn. Ẹnyin kò ha san jù wọn lọ?" Ronu nipa awọn amọtẹkun ti n gbe ilẹ yinyin, nibi ti yinyin n bo ohun gbogbo mọlẹ. Ọlọrun n pese ounjẹ fun wọn. Eniyan ni o n ṣe aniyan ti o si n ṣe aisinmi nipa riri ounjẹ ti o to jẹ, ṣugbọn Jesu wi pe, "Ẹ tète mã wá ijọba Ọlọrun na, ati ododo rẹ" – Oun yoo si pese ohun gbogbo ti a ṣe alai ni.

O ti ka iroyin nipa ogo aafin Sọlomọni. Awọn eniyan n mú ọrọ̀ nla ati iṣura iyebiye lati orilẹ-ède pupọ wa, ki Sọlomọni le maa gbe igbesi-aye igbadun ati faaji. Ṣugbọn Jesu wi pe a ṣe awọn itanna igbẹ paapaa lọṣọ ju u lọ.

**"O ṣe lili igbẹ́ lọṣọ, O fi òórùn didun si itanná rẹ̀**

**kọọkan; Bi o bá fẹran awọn itanná kékèké bẹẹ,**

**Emi mọ̀ pe O fẹran mi daradara."**

**Didariji Awọn Onigbese Wa**

"Dari gbese wa jì wa, bi awa ti ndariji awọn onigbese wa." Jesu dari ẹṣẹ wa ji wa, Oun si n fẹ́ ki a dariji awọn wọnni ti wọn ti ṣe wa ni ibi ni ọnakọna. A ko le reti pe ki Oluwa ṣe ohunkohun fun wa bi a bá ni ikunsinu kan si ẹlomiran. A tilẹ gbọdọ lọ si ọdọ arakunrin wa ki a si mu awọn nnkan bọ̀ si titọ́, bi a ba mọ pe oun ni nnkan kan sinu si wa. Nigba ti kò ba si ohun kan laaarin awa ati awọn ẹlẹgbẹ wa, a le reti pe ki Ọlọrun gbọ́ ki O si dahun adura wa.

A gbọdọ ṣọra ki a si gbadura nigba gbogbo ki idanwo ma ba le bori wa. A le fẹran Oluwa, ki a si ni ipinnu lati sin In; ṣugbọn Jesu wi pe lootọ ni ẹmi n fẹ, ṣugbọn o ṣe ailera fun ara. A gbọdọ maa gbadura lojoojumọ fun agbara lati wà fun Jesu, ati ki a si le bori gbogbo idanwo.

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni itumọ ṣiṣe itọrẹ aanu?
2. Ọna wo ni agabagebe n gbà ṣe itọrẹ aanu?
3. Ọna wo ni Jesu kọ́ wa?
4. Ọna wo ni agabagebe n gba gbadura?
5. Kọ́ "Adura Oluwa" sori.
6. Bawo ni a ṣe le to iṣura jọ si Ọrun?
7. Ki ni Kristi ṣeleri fun wa, bi a bá kọ́ wá Ijọba Ọlọrun?